# Ìlo Ẹ̀rọ Ìgbàlódé Fún Kíkọ́ Ewì Alohùn Yorùbá ní Àkọ́yege: Àgbéyẹ̀wò Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ní àwọn Ilé-Ẹ̀kọ́ Gíga Ìpínlẹ̀ Èkó

*Akanmu, Dayo & Adeniyi, Sakiru*


## Àṣamọ̀

*Ṣíwájú àkokò yìí, Ọ̀pọ awon olùkọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá ni kò mọ̀ pé a lè ṣàmúlò yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún kíkọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ìgbàgbọ wọn ni pé iyàrá-àyẹ̀wò èdè wà fún àwọn ède ilẹ̀-òkèèrè bí i Gẹ̀ẹ́sì, Faransé, Sípáníìṣí, Pọtugí ati Arábîkì (Lárúbáwá). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé lónìí, ọ̀pọ̀ àwọn olùkọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá ló ní ìmọ ẹ̀rọ-ayárabíàṣà, ẹ̀rọ-ìbánisọ̀rọ̀ ero-alátagbà, àti ẹ̀rọ-ìbanidọ́rẹ̀ẹ́ bí i Wásaàpù, Fesibúùkù, Mẹ́sẹ́ńjà, Túítà, Yútuùbù, Ínsítàgíráàmù ati Tẹ́lígíráàmù, iye àwọn tó ń ṣàmúlò gbogbo àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyí pẹ̀lú ìlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún kíkọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá ní àkọ́yege kò tó nǹkan. Ogunlọ́gbọ̀n àwọn onímọ̀ bí Ruby (2004), Mambo (2004), Beder (2008) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ló ti ṣe iṣẹ́ lóri yàrá-ẹ̀kọ́-èdè. Ohun tí ó wọ́pọ̀ nínú iṣẹ́ gbogbo àwọn wọ̀nyí ni pé àwọn èdè ilẹ̀-òkèèrè nìkan ni wọ́n gbà pé a lè lo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún àti pe ẹ̀kọ ajẹmédè nìkan ló wà fún. Iṣẹ́ yìí fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé kìí ṣe àwọn ède ilẹ̀-òkèèrè àti ẹ̀kọ ajẹmédè nìkan ni a lè ṣàmúlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún, a le ṣàmúlo rẹ fún àwọn èdè àbínibí àti ẹ̀kọ ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ bákan náà. Ìyànjú láti mọ ohun tí yàrá-àyẹ̀wò èdè jẹ́, ìwúlo rẹ̀ àti bí a ṣe lè lò ó fún kíkọ́ ewì alohùn Yorùbá ní àkọ́yege ni ó ṣokùnfà àpilẹ̀kọ yìí. Láti rí àrídájú pé ó ṣeéṣe kí á lo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún kíkọ́ ewì alohùn ní àkọ́yege, a ṣe àbẹ̀wọ̀ sí yàrá-ẹ̀kọ́-èdè Ifásitì ti ìpínlẹ̀ Èkó (LASU) àti Ifásitì ti Ìpínlẹ̀ Èko Ajẹmọ́-ètò-ẹ̀kọ́ (LASUED): Ọ̀tọ̀/Ìjàníkin àti Ẹ̀pẹ́, a sì fi ọ̀rọ̀ wá àwọn olùkọ́ méjì-méjì ní àwọn Ifásitì yìí lẹ́nu wò nípa bí àmúlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún kíkọ́ ewì alohùn Yorùbá ti rí ní ọ̀dọ wọn. A sì ṣàmúlo ogún akẹ́kọ̀ọ́ ède Yorùbá (onípele kejì àti ìkẹta) láti mọ bí ìlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún kíkọ́ ewì alohùn Yorùbá ṣe kúnjú òṣùwọ̀n sí, a sì ṣe àtúpalẹ̀ détà wa nípa sàtísítìkì. Àbájáde Ìwádìí wa fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé gbogbo àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga tí a ṣe àbẹ̀wò sí ni ó ní yàrá-ẹ̀kọ́-èdè, àwọn olùkọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá tí wọ́n ń ṣàmúlọ̀ wọn kò ju ìdá ogún nínu ìdá ọgọ́rùn-ún. Ó tún fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé yàrá-ẹ̀kọ́-èdè rọrùn láti fi kọ́ ewì alohùn ju kí olùkọ́ kàn máa pariwo ẹnu lásán àti fi àkokò ṣòfò lọ. Àti pàápàá gbogbo olùkọ́ lítíréṣọ̀ àti ède Yorùbá nílo láti kọ́ bí a ti ṣe ń ṣàmúlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè àti àwọn ẹ̀rọ ìgbàlódé inú rẹ̀ fún èkọ́ àkọ́yege kí á máa ba di òpè nínu ṣíṣàmúlò oríṣiiríṣii ẹ̀rọ amẹ́kọ̀ọ́yéni tí ó wà lode òní.*


*Ọ̀rọ̀ tó ṣe kókó:* *yàrá-àyẹ̀wò èdè, ewì alohùn, lítíréṣọ̀, ẹ̀rọ-amẹ́kọ̀ọ́yéni, ìgbàlódé.*

## Ìfáàrà

Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè jẹ́ iyàrá tí a pèse àwọn ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán sí láti mú kí ẹ̀kọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ rọrùn; ìrọ̀rùn yìí kì í ṣe fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nìkan bí kò ṣe fún àwọn olùkọ́ náà pàápàá. A ṣí yàrá-ẹ̀kọ́-èdè àkọ́kọ́ ní Fásitì ìpínlẹ̀ Louisiana lọ́dun 1947.

A ṣe àkíyèsí pé ó níra láti rí ọ̀pọ̀ àwọn olùkọ́ lítíréṣọ̀ ede Yoruba ní ilẹ̀-Adúláwọ̀ tí ó ń lo yàrá-àyẹ̀wò èdè fún kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nítorí ọ̀pọ̀ ni òye ohun tí yàrá-àyẹ̀wò èdè wà fún kò fi bẹ́ẹ̀ yé yékéyéké. Ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga miíràn, yàrá-ìdanilẹ́kọ̀ọ́ lásán lọ̀pọ̀ olùkọ́ lítíréṣọ̀ àti ède Yorùbá rí i sí, bẹ́ẹ̀ ọ̀pọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ ló ń pòǹgbẹ̀ láti mọ bí a ti ṣe ń lo yàrá-àyẹ̀wò èdè àti bí àwọn ṣe lè jẹ àǹfàní rẹ̀ ṣùgbọ́n àbánikándá ni èyí jẹ́ fún púpọ̀ wọn.

Iṣẹ́ yìí yóò ṣe òfíntótó nípa ìlo ẹ̀rọ-ìgbàlódé fún kíkọ́ ewì alohùn Yorùbá ní àkọ́yege nípa ṣíṣe àgbéyẹ̀wò àwọn yàrá-àyẹ̀wò èdè ilé-ẹ̀kọ́ gíga ìpínlẹ̀ Èkó. Nínú iṣẹ́ yìí ni a o ti mọ̀ bóyá yàrá-àyẹ̀wò èdè dúró gẹ́gẹ́ bíi yàrá-ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lásán tàbí ó gbòòrò jù ú lọ. Bébà yìí kò ní ṣàìtan ìmọ́lẹ̀ sí awuyewuye wí pé yàrá-àyẹ̀wò èdè kò pójú òṣùnwọ̀n tó láti kọ́ lítíréṣọ̀ Yorùbá àti pé ṣé ọgbọ́n ìkọ́ni ló jẹ́ tàbí èròjà amẹ́kọ̀ọ́yéni ni. Ní àkotán, bébà yìí yóò jẹ́ ká mọ̀ bóyá gbogbo àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga ìpínlẹ̀ Èkó tí a gbé yẹ̀wò fún iṣẹ́ yìí ni wọ́n ní yàrá-àyẹ̀wò èdè ati oríṣi ẹ̀rọ inú rẹ̀ tàbí wọn kò ní. Àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga ìpínlẹ̀ Èkó tí a gbé yẹ̀wò fún iṣẹ́ yìí ni Ifásitì ìpínlẹ̀ Èkó, Ilé-ẹ̀kọ àgbà àwọn olùkọ́ ti Ìjàníkin àti Ẹ̀pẹ́.

## Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè

Ó yẹ kí á jẹ́ kó di mímọ̀ pé a kò ka yàrá-àyẹ̀wò èdè mọ́ àwọn ọgbọ́n-ìkọ́ni rara, fún ìdí èyí, yàrá-àyẹ̀wò èdè kìí ṣe ọgbọ́n-ìkọ́nilède bí ko ṣe ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni tó ń mú kí ẹ̀kọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ di ìrọ̀rùn fún tolùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ èdè. (Perez-Paredes, 2002:60). Ó tẹ̀ síwájú pé, yàrá-àyẹ̀wò èdè jẹ́ iyàrá tí a pilẹ̀ ṣe fún kíkọ́ àwọn èdè àtọ̀húrìnwá, tí a sì ró o lágbara pẹ̀lu ẹ̀rọ-akáhùnsílẹ̀, ẹ̀rọ-akáhùnkáwòrán, tàbí ẹ̀rọ-ayárabíàṣà tí a sopọ̀ mọ́ra wọn láti lè ṣe é ṣe fún olùkọ́ láti gbọ́ àti láti bá àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sọ̀rọ̀.

Ruby, W.B. (2004) sọ pé, yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ni àgbékalẹ̀ ẹ̀rọ ìmóhùn tàbí ìmóhùn-máwòrán tí à ń lò láti ṣe ìrànwọ́ fún kíkọ́ èdè lóde òní. A lè rí yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́, Ifásitì, àti àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga.

Mambo (2004) sọ pé, yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ni ibi tí a pèsè sílẹ̀ láti mú kíkọ́ èdè ilẹ̀-òkèrè rọrùn. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ẹ̀rọ àtijọ àti tòde òní ló jẹ́ àwọn nǹkan tí a máa ń bá ní yàrá-ẹ̀kọ́-èdè, lára àwọn ẹ̀rọ yìí ni ẹ̀rọ aká-ohùn-sílẹ̀, ẹ̀rọ aká-ohùn-káwòrán-sílẹ̀, tàbí ẹ̀rọ-ayárabíàṣá. Wọ́n máa ń pèse àǹfàni sọ-n-gbọ́ pẹ̀lú èròńgbà ṣíṣe ìgbọ̀wọ́ fún gírámà, ọ̀rọ̀ tuntun, àti ìhun gírámà tí a ti kọ́ nínu ìyárà-ìdánilẹ́kọ̀ọ́.

Beder (2008) wí pé, yàrá-ẹ̀kọ́-èdè jẹ́ iyàrá kan nínu ilé-ẹ̀kọ́, ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga, Ifásitì, tàbí ilé-ẹ̀kọ́ èdè tí ó ní àwọn àṣàyàn ohun-èlò àti ẹ̀rọ láti ran àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ède ilẹ̀-òkèèrè lọ́wọ́ láti kọ́ àwọn èdè náà nípa títẹ̀tí sí fọ́nrán, wíwo fídíò, kíká ohùn ara wọn sílẹ̀.

Ní àfikún sí ohun tí gbogbo àwọn onímọ̀ yìí mẹ́nubà nípa yàrá-ẹ̀kọ́-èdè àti àkóónú rẹ̀, ìwádìí wa fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé kìí ṣe àwọn ède ilẹ̀-òkèère nìkan ni a lè ṣàmúlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún, a lè ṣàmúlo rẹ̀ fún àwọn èdè àbínibí wa bákan náà, àti

pàápàá, yàrá-ẹ̀kọ́-èdè kò pin sóri ẹ̀kọ́ ajẹmédè, ó kúnjú òṣùwọ̀n fún ẹ̀kọ ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ bákan náà. Ní àfikún sí àkóónú yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ni ẹ̀rọ-ayélujára tòun pátákó-ìkọ̀wé oníná/onímọ̀-ẹ̀rọ tún jẹ́ àkóónú yàrá-àyẹ̀wò èdè lónìí.

Èrò méjì ló wà lórí èyí, èrò kán gbà pé a kò lè lo yàrá-àyẹ̀wò èdè fún gbogbo àwọn ọgbọ́n-ìkọ́nilédè nígbà tí èrò kejì gbà pé yàrá-àyẹ̀wò èdè wúlò fún gbogbo ọgbọ́n-ìkọ́nilédè. Perez-paredes (2002:60) jẹ́ ọ̀kan lára àwọn onímọ̀ tó tako èrò pé yàrá-ẹ̀kọ́-èdè wúlò fún gbogbo ọgbọ́n-ìkọ́nilédè, Perez-paredes gbà pé ọgbọ́n-ìkọ́nilédè tí o fara pẹ́ yàrá-àyẹ̀wò èdè tabi èyí tí yàrá-àyẹ̀wò èdè dára fún jùlọ ni Ọgbọ́n-ìkọ́ni amóhùnmédè. Àbájáde ìwádìí wa tako èro Perez-paredes (2002), nítorí pé gbogbo ọgbọ́n-ìkọ́nilédè pátá ni yàrá-àyẹ̀wò èdè dára fún níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé yàrá-àyẹ̀wò èdè kìí ṣe ọgbọ́n-ìkọ́ni bí ko ṣe ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni. Nítorí pé ó jẹ́ ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni, kò sí irú ọgbọ́n-ìkọ́nilédè tí kò ní lè wúlò fún; ìlo rẹ̀ pẹ̀lu èyíkèyí àwọn ọgbọ́n-ìkọ́nilédè wà lọ́wọ dídáńgájíyá olùkọ́ èdè nínu bí ó ṣe mọ yàrá-ẹ̀kọ́-èdè lò sí.

## Oríṣiiríṣii yàrá-ẹ̀kọ́-èdè

Onírúurú yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ni ọ̀pọ̀ àwọn onímọ bí Perez-paredes (2002), Ruby (2004), Mambo (2004), Beder (2008), Maheshwari (2016) mẹ́nubà pé o wà ṣùgbọ́n méta tó gbajúmọ̀ jùlọ la óò mẹ́nubà.

- Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè jẹ̀lẹ́ńkẹ́
- Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè gbọ́-kín-fèsì
- Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ìgbàlódé

*Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè jẹ̀lẹ́ńkẹ́*: Irúfẹ́ yàrá-ẹ̀kọ́-èdè yìí ló máa ń ní ẹ̀rọ-ayífọ̀rán àti amóhùnbúgbàmù láti lè jẹ́ kí gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ lè gbọ́ fọ̀rán náà ketekete.

*Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè gbọ́-kín-fèsì*: Irúfẹ́ yàrá-ẹ̀kọ́-èdè yìí máa ń ṣàmúlò agbóhùnsétí-alágbèékari, èyí ni olùkọ́ àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lò láti gbọ́ ara ẹni yé yékéyéké.

*Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ìgbàlódé*: Gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, yàrá-ẹ̀kọ́-èdè yìí ló wọ̀pọ́ lóde-òní. Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè yìí máa ń ní àyè-akópa níbi tí akẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan yóò jókòó sí, iye àyè-akópa wà lọ́wọ bí yàrá-ẹ̀kọ́-èdè náà bá ṣe tóbi si, ó wá kéré pin, kò gbọdọ̀ dín ni ógún. Àyè-akópa kọ̀ọ̀kan ló máa ń ní ẹ̀rọ-akáhùnsílẹ̀, agbóhùnsétí-alágbèékari, gbohùngbohùn, ẹ̀rọ-ayárabíàṣà, pátákó-ìkọ̀wé oníná/onímọ̀-ẹ̀rọ (ọ̀kan fún gbogbogbò), àti àwọn ẹ̀rọ́ òmíràn tí a so pọ̀ mọ́ ẹ̀rọ-ayélujára láti lè mú kí ó rọrùn fún olùkọ́ láti ṣàfihàn fọ̀rán kan náà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní àyè-akópa kọ̀ọ̀kan.

## Àǹfàni yàrà-àyẹ̀wò èdè

- *Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè jẹ́ toní ṣe-kí-n-wò-ọ́*: ohun tí ènìyàn mọ̀ nípa ìwé kíkà nìkan kò dàbí èyí tí ènìyàn ká, tí ó sì fi sí ojúṣe nípa ṣíṣe àfihàn rẹ̀ fáráyé. Àǹfàní àkọ́kọ́ tí yàrá-àyẹ̀wò èdè n fúnni nìyí.
- *Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè máa ń jẹ́ kí ẹ̀kọ́ tètè yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yékéyéké sí i*: Èyí rí bẹ́ẹ̀ nígbà tó ṣe pé yàrá-àyẹ̀wò èdè fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láyè láti kópa dáadáa lásìkò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tó mú kí wọ́n fi gbogbo ọkàn àti iyè wọn sí iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe. Kí á má ṣe gbàgbé ípèdè Gẹ̀ẹ́sì yìí tó wí pé, “mò ń gbàgbé ohun a bá sọ fún mi, ohun mo bá ri ni mò ń mọ̀, ohun mo bá ń ṣe ni mò ń rántí.”
- *Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè máa ń fún akẹ́kọ̀ọ́ èdè ní ìgboyà*: Akẹ́kọ̀ọ́ tí ẹ̀kọ́ ti yé yékéyéké, tí ó sì ti ṣe àfihàn ohùn ti a kọ́ ọ nípa *ṣe-kí-n-wò-ọ́*, dájúdájú, irú akẹ́kọ̀ọ́ náà yóò ní ìgbàgbọ́ àti ìgboyà nínú ara rẹ̀ ní èyí tí yóò jẹ́ kó ṣe é ṣe fún un láti dá dúró nínú ẹ̀kọ rẹ̀ láì jẹ́ àfomọ̀ mọ́.
- *Ó máa ń mú kí iṣẹ́ olùkọ́ di ìrọ̀rùn*: Èyí ni pé olùkọ́ kò nílò àti fẹ̀fun tàbí làágùn tàbí ṣe làálàá jìnnà kí ohun tó ń sọ tó yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yékéyéké.
- *Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè kì í fi àkokò ṣòfò rárá àti rárá*: Nígbà tí ohun tí olùkọ́ ń sọ bá tètè yé àwọn akẹ́kọ̀ọ́, olúkọ̀ ò nílò láti làágùn jìnnà fún ìdí èyí àsìkò fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yóò tó ni àtóṣẹ́kù ati pe yóò tún fàyè gba ọ̀pọ̀ ṣe-kí-n-wò-ọ́ sí i tí yóò túbọ̀ jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ túbọ̀ di àràbà sí i nínú ẹ̀kọ́ náà.
- *Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè máa ń fún àtolùkọ́ àtakẹ́kọ̀ọ́ ní àǹfàní láti bẹ́gbẹ́ pé lágbàáyé:* Nígbà tó ṣe wí pé èyí ni ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni tó pàtàkì jùlọ táwọn orílẹ̀-èdè tó ti gòkè-àgbà ń ṣàmúlò fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́, èyí yóò jẹ́ kí àwa náà bẹ́gbẹ́ pé pẹ̀lu àwọn orílẹ̀-èdè yìí.

## Ìpènijà Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún Ède Yorùbá

Ọ̀pọ onímọ̀ ède àbínibí bíi Aziza (2010), Obioma (2010) àti àwọn mìíràn ni wọ́n gbà pé ìṣòro gbòógì tó ń kojú ẹ̀kọ́ ède abínibí ni àìtó oríṣi ohun-èlò ìkọ́ni yàtọ̀ sí ìwé kíkà ti o jẹ́ gbóògì nínu ohun-èlò ìtọ́kasí tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tẹramọ́ lílo rẹ̀ ju èyí tí kò rí bẹ́ẹ́ pẹ̀lu àwọn ède ilẹ̀-òkèèrè. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn olùkọ́ mìíràn gbà pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó yè kooro kan kò lè fìdí múlẹ̀ láì sí ìwé kíkà bíi iyanrìn etí-òkun gẹ́gẹ́ bi ó ti wà fún àwọn èdè ilẹ̀-òkèèrè láìmọ̀ pé àwọn onítọ̀hún tún ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ohun-èlò ìkọ́ni mìíràn yàtọ̀ sí ìwé.

Ó ṣeni ní kàyéfì wí pé nígbàkúùgbà tí àwọn onímọ̀ èdè abínibí bá ń dárúkọ ohun-èlò ìkọ̀ni, a kìí mẹ́nuba yàrá-ẹ̀kọ́-èdè èyí sì jẹ́ ìpènijà ńlá fún yàrá-àyẹ̀wò èdè àti ède Yorùbá. Ìpènijà àkọ́kọ́ ni pé, ọ̀pọ̀ onímọ̀-èdè àbínibí pàápàá jùlọ ède Yorùbá òní kò mọ̀ pé ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni ni yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ń ṣe, pé kìí ṣe ọgbọ́n-ìkọ̀ni.

Ìpènijà kejì ni pé, ọ̀pọ̀ olùkọ́ lítíréṣọ̀ àti èdè Yorùbá òní ní òye wọn kò fi bẹ́ẹ̀

kún tó lóri ohun tí yàrá-àyẹ̀wò èdè jẹ́. Èyi ló ṣokùnfà ìpènijà kẹta tó dá lóri pé púpọ̀ àwọn olùkọ́ yìí ni kò mọ bí a ti ṣe ń lo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè àti pé wọn rí ìṣàmúlò rẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi idán.

Ìpènijà yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fun èdè Yorùbá tó dàbi alárà ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga wa ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá òde òní lòrùngbẹ ìlo yàrá-àyẹ̀wò èdè ń gbẹ, ọ̀pọ̀ ni kò ní àǹfàní sí yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga wọn yálà nípa pé wọ́n kò ní rárá tàbí kí wọ́n ní bíi aláìní, tàbí kí ibi tó wà jìnnà réré sí ẹ̀ká-ẹ̀kọ́. Ìwádìí wa fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé Ifásitì ti Ìpínlẹ̀ Èkó ajẹmọ́ ètò-ẹ̀kọ́ ti Ìjàníkin (LASUED Oto/Ijanikin) nìkan nínu àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga ìpínlẹ̀ Èkó mẹ́ta tí a gbé yẹ̀wò fún iṣẹ́ yìí ló ní yàrá-àyẹ̀wò èdè tó dáńgájíá; Ifásitì ti ìpínlẹ̀ Èkó (LASU) náà ti ní èyí tó dáńgájíá rí ṣùgbọ́n tí ìṣàmúlò rẹ̀ rí ségesège báyìí. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwóọn aláṣẹ ilé-ẹ̀kọ́ náà fẹ́ràn láti máa lò ó ní gbogbo ìgbà fún iyàrá-ìdánwò orí-afẹ́fẹ́ (síí Bii Tìì) èyí tí wọ́n gbàgbọ́ pé ó ń pa owó wọlé fún wọn ju ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ èdè (Yorùá) lọ. Ní ti Ilé-ẹ̀kọ àgbà àwọn olùkọ́ ti Ẹ̀pẹ́, àwọn wọ̀nyí ní bíi aláìní nítorí ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ kìí lò ó, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gan kò mọ̀ nípa rẹ, àti pé ibi tó wà jìnnà réré sí ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ wọn. Kí wọ́n tó lè ṣe àmúlò rẹ̀ wọ́n kọ́kọ́ ní láti fi owó wọ ọkọ̀ dé ibi tí ó wà ni.

## Yàrá-ẹ̀kọ́-èdè àti Ìṣàmúlò Rẹ̀ fún Ewì Alohùn Yorùbá

Ọ̀pọ̀ àwọn olùkọ́ tí ó ń kọ́ ewì alohùn Yorùbá lè máa rò pé ǹjẹ́ ó ṣeéṣe láti ṣàmúlò yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún ìkọ́ni ewì alohùn Yorùbá? Ìwádìí fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé ó ṣeéṣe dáadáa. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìdá ogún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún àwọn olùkọ́ ewì alohùn Yorùbá ní àwọn Ifasítì ti Ìpínlẹ̀ Èkó (LASU àti LASUED) ló ń ṣàmúlo tàbí ló ti ṣàmúlò yàrá-ẹ̀kọ́-èdè rí láti fi kọ́ ewì alohùn Yorùba, ìwọn ìba ìdá ogún yìí, ni a ti fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé kì í ṣe pé ó ṣe e ṣé nìkan láti ṣàmulo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún ìkọ́ni ewì alohùn sugbon ohùn gan-an ni ohun-èló ìkọ́ni tó dára jùlọ láti kọ́ ewì alohùn Yorùbá. Ó yẹ kí á sì rántí pé yàrá-ẹ̀kọ́-èdè kì í ṣe ọgbọ́n-ìkọ́ni bí ko ṣe ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni èyí tí ó wà fún èyíkèyí ọgbọ́n-ìkọ́ni tí a bá yàn láàyò láti fi kọ́ ewì alohùn Yorùbá. Síwájú sí i, ohun tí ó ṣe gbòógì nínu yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ni *gbọ́-n-sọ bó ti tọ́ àti bó ti yẹ*; gbọ́-n-sọ yìí náà ló jẹ ìkọ́ni ewì alohùn Yorùbá lógún, ìyẹn ni *pípe ohùn bí olóhùn ti ń pè é*. Kò ṣe àjèjì sí wa pé bí a ti ní ìpohùn ìsọ̀rọ̀kéwì náà ni a ní ti àrángbọ́/ìwáhùnroro, bákan náà sì ni a ní ti orin. Ohùn ti a ń lò fún ifá kíkì yàtọ̀ sí ti ìjálá ọdẹ; ti ẹ̀sà pípè kò jọ tàrùngbè; tẹkún ìyàwó yàtọ̀ sí ti rárà; toríkì kò jọ tọfọ̀; ti bọ̀lọ̀jọ̀ ko jọ ti obintu abbl.

Yóò nira fún olùkọ́ ewì alohùn Yorùbá láti jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mú ohùn ewì alohùn kọ̀ọ̀kan nínú yàrá-ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àti pàápàá, yóò là á lóòógùn tòun okùn púpọ̀ kí á tó lè fi agbárákáká rí ìda ogún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí yóò mú ohùn ewì alohùn náà, abálájọ tí ọ̀pọ̀ onímọ̀ ède Yorùbá jẹ́ òǹkọ èwí tó jẹ́ pé àwọn apohùn inú wọn kò tó nǹkan. Lóòótọ́ èyí kìí ṣe ẹjọ́ àwọn olùkọ́ nítorí pé kìí ṣe gbogbo wọn ló ní àǹfàní kíkọ́ ohùn nígbà tí wọ́n wà nílé-ẹ̀kọ́ àti pé ọ̀pọ̀lọpọ̀

wọn kọ́ ló ní ẹ̀bùn ohùn tàbí wá láti ìdílé tí a ti ń pohùn; ohun tí ènìyàn kò sì mọ̀ kò lè fi kọ́ ẹlòmíràn àyàfi tí wọ́n bá gba àwọn apohùn láti máa kọ́ àwọn àkẹ́kọ̀ọ́ wọn.

Àwọn ewì alohùn Yorùbá ìsàlẹ̀ yìí ni a ti gbìyànjú láti kọ́ àwọn ogún akẹ́kọ̀ọ́ nínu yàrá-ìdánilẹ́kọ̀ọ́ (bí àṣà) àti yàrá-ẹ̀kọ́-èdè ní Ifásitì ti Ìpínlẹ̀ Èkó ajẹmọ́ Ètò-ẹ̀kọ́ (LASUED Oto/Ijanikin) nítorí òun nìkan ni ìwádìí fi hàn pé ó ní yàrá-ẹ̀kọ́-èdè tó ń ṣiṣẹ́ dáadáa:

1.

Ọjẹ́kúnlé ò, ṣ'ó ń rí nǹkan!
Ayé gbìyànjú, wọ́n yí mi láwọ̀ padà kíákíá
Ayé, ayé yìí ò ṣẹ!
Ayé níí gún'yán eérú
Ayé níí rokà eèpè
Báyé ṣènìyàn tán
Wọ́n á tẹsẹ̀ mọ́'rìn kíákíá
Ayé ló ṣ'Agbe tó daláró igbó o
Ayé ṣ'Àlùkò, tó d'olósùn ẹgàn
Ayé ò ní ṣe yín, ẹ ò ni ṣìṣe,
Ayé ló ṣe mí tí mo d'Erè láàkọ́kọ́ ọjọ
Bí ò bá sí iṣu, kí la ó máa pè ní'yán?
Bí ò bá sí èlùbọ́, kí la ó pè lámàlà?
Bí ò bá sí àgbàdo kí la á pè lẹ́kọ yangan?
Ọpẹ́lọpẹ́ orí bàbá mi, un náà ló yọ mi
Nígbà tí mo d'Erè láàkọ́kọ́ ọjọ́
Ìgbà tó tún d'ẹlẹ́ẹ̀kejì yìí ńkọ́?
Kin ní ọ̀hún tún ti yíwọ́ o, ará ìlú ù mi!
Ọjẹ́kúnlé, wá súré relé
O ó bá mi délé bàbá mi
Àdó kan ń bẹ l'ájà a-mi-lo-lo-lo
Ìgbà tó o bá mú u dé
Gbogbo rẹ̀ yóò sì ṣ'ẹnu're

Ará àlògbó, ọmọ ẹkùn ní'Bá
Ayé binú kán-ún, wọ́n sọ kán-ún s'ómi
Ayé bínú iyọ̀, wọ́n po'yọ̀ m'éèpè
Ayé bínú Ọjẹ́lànàdé,
Wọ́n yí i láwọ̀ padà kíákíá.
( Eegun Alare )

2. (a) Ìbà okó tó doríkodò tí ò ro
Ìbà ìyámọ̀pó tó doríkodò tí ò ṣẹ̀jẹ̀
Má jẹ́ ó ṣú mi í ṣe o
Má jẹ̀ ń ṣìṣe níbẹ̀ o
Má játùpà Ògún ó tìdí jò mọ́ n lọ́ọ̀.

(b) Ìbà o o o!
Ọlọ́jọ́ òní mo júbà k'íba mi kó máa ṣẹ
Ìbà lọ́wọ́ Olódùmarè a gb'ọ̀tún
Atẹ́ní lẹ́bẹ́lébẹ́ ṣagbeji ara
Mo júbà k'íbà mi kó máa ṣẹ
Ìbà apẹ́tẹ́ ọwọ́
Ìbà pẹ̀lẹ̀m̀bẹ̀ ẹsẹ̀
Ìbà àpẹ́tẹ́lẹrísẹ̀ tí ò hunrun tó fi dé pọọlọ itan
Ọlọ́jọ́ òní mo júbà k'íbà mi kó máa ṣẹ
Ìbà alájá t'òun t'ògbóró
Ìbà ẹlẹ́ṣin t'òun t'èèkàn lẹ́sẹ̀
...bí labalábá bá jáko a sì júbà ẹyẹ oko
Àgbẹ̀ jáko a sì júbà kùẹ̀kùẹ̀
Àgbẹ̀ tó jáko tí ò júbà kùẹ̀kùẹ̀
Ọkọ́ a ṣá wọn lójúgun
Ọlọ́jọ́ òní mo júbà k'íbà mi kó máa ṣẹ.
(Àlàbí Ògúndépò ń sun ìjálá, Apá kìíní- you tube; 27 Jul. 2015)
(d) Àwa ara wá rírà wa

Àwa ara wá ríra wa
Ológìní rọ́mọ ẹkùn
Àwa ara wá ríra wa
Ẹ dúró ná ẹ̀yín ará mi o
Níbo nilé Ògún?
Ìré nilé Ògún.
Irọ́ lo pa ìrọ̀ lo ṣùtà, alábàrí lo rí lo pè lélégbo
Ìré kọ́ nilé Ògún
Ẹmu lÒgún yà mu bẹ.

3. Ìyá mi bàbá mi, ilé ọkọ́ yá
Mo wá gbare mi kí n tó máa lọ
Ṣe bémi lọmọ Ìkòyí-ẹ̀ṣọ́
Níwòyí oṣù mẹ́sàn-án òní,
Oúnjẹ ọmọ ni kẹ́ ẹ wá bá mi jẹ
Kí n bísun, kí n bíwàlẹ̀ nílé ọkọ
Kí n má fàbíkú ṣẹwọ́
Kẹ́yìn mí mámà mẹni
Àdùnní ọ̀rẹ́ mi,
Mi bémi ìrẹ la jọ jiyán búnibúni
Mi bémi ìrẹ la jọ jikà gànyàngànyàn
Mi bémi ìrẹ la jọ wọṣọ má bẹ́rẹ̀ yídò
À ò tún ní ríra déedée mọ
Me bémi nìgbín ọkọ mi nìkòkò,
Alẹ́ òní ni yóò dé mi mọ́lẹ̀ porongodo
Me bémi nìtàkùn ọkọ mi lọ̀kẹ́rẹ́,
Alẹ́ òní ni yóò tọ̀ mí látọ̀pin
Iyè mi o, ba à mi oo
Mo gbọ́ pé ilé ọkọ ilé ẹ̀kọ́ ló jẹ́
Báa gúnyán, wọ́n á ló dín kókó
Báa gélùbọ́, wọ́n á léètà dà sí

Báa rokà, wọ́n á ló rọ̀ bẹ̀tẹ̀bẹ̀tẹ̀
Báa kí wọn, wọ́n á ní a ò mọ̀nìyàn kí
Kí ń mórí lọ, kí n múwà relé ọkọ
Kílà ń ṣe?
Kílà ń ṣe?
Ta fi ń mọ̀wà hù nílé ọkọ.

4. (a) Gbírígbírí là ń yídó
Gbìrìgbìrì là ń yíkòkò
Odó nigi, ìkòkò lamọ̀
Báa yíkòkò bẹ́ẹ̀ inú alámọ̀ a bàjẹ́
Ọ̀kan ṣoṣo póró lobìrin ń dùn mọ lọ́wọ́ ọkọ....
(Àwọn ojú-odù mẹ́rìndínlógún)

(b) ....................
Adíá fún ọ̀làlà tí ń ṣawo ọ̀bẹ
Ló dífà fún ọ̀bẹ
Ọ̀bẹ́ ṣọdùn nìín tán
Wọ́n ní kò ní ṣe tẹ̀míì
Ẹbọ lọ́ ní kó wá ṣe
Ọ̀làlà ìwọ lawo ọ̀bẹ
Àwá ṣọdùn nìín tán
A óò tún se tẹ̀míìn
Ọ̀làlà ìwọ lawo ọ̀bẹ

5. (a) Ògbómọ̀ṣọ̀ Ajílété
Ògbómọ̀ṣọ̀ ìlu akin
Ògbómọ̀ṣọ́ tá a tẹ́ sáàárìn ọ̀dàn
Ibi a gbé n jekà ká tó mùkọ yangan
Ìlú àbò fẹni ẹ̀rù ń bà
Ọmọ Ṣòhún
Mọdé ń jagun níta, ògùn ń gùn ún níyàrá.....

(b) Ẹ̀gbá ọmọ Líṣàbí Agbòǹgbo-àkàlà
Ọmọ erín jogún ọlá
Ọmọ òṣílẹ̀kùn tilẹ̀kùn pa
Ọmọ ajógbẹrú máà jó gbẹ̀kọ……..

(d) Ìbàdàn mesìọ̀gọ̀ nílé Olúyọ̀lé
Ìlú Ògúnmọ́lá olódògbòdo kẹríkẹrì lójú ògún
Ìlú Ìbíkùnlé alágbàlá jáyàjáyà
Ìlú Àjàyí ó gbórí ẹfọ̀n ṣe fílafìlà
Ìlu Látòósà àrẹ-ọ̀nà kakanfò
Ìbàdàn ọmọ ajòrosùn…….

6. (a) Afẹ́fẹ́ tí ń gbére pàde olókun
Máà gbére pàde olókun mọ́ o
Èmi Adéwálé ni kó gbére pàdé
Afẹ́fẹ́ tí ń gbére pàde ọlọ́sà
Máà gbére pàde ọlọ́sà mọ́ o
Èmi Adéwálé ni kó gbére pàdé

(b) Wọ́n ní Ọ̀rúnmìlà, ọ̀tá rè é níwájú
Ó ní iwájú iwájú lọká ń foró sí tó fi ń pani
Wọ́n ní Ọ̀rúnmìlà, ọ̀tá rè é lẹ́yìn
Ó ní ẹ̀yìn ẹ̀yìn làkéke ń fìja tirẹ̀ sí
Wọ́n ní Ọ̀rúnmìlà, ọ̀tá rè é láàárín
Ó ní Ṣàngó ò mẹni àárín
Ọmọdé ló bá ń perí àwa nibi
Igbe rara làrá ń ké wọlẹ̀, igbe rara…..

7. (a) Yànmùyánmú gbòde o, Ológbòjò yẹra
Yànmùyánmú gbòde o, Ológbòjò yẹra
Ó gbé lórọ́gbà ó mí worò
Ó gbé lórọ́gbà ó mí worò
Ìyá àgbà ògbó àjẹ́

Ìyá àgbà ògbó àjẹ́ o

Ó gbé lórọ́gbà ó mí worò.

(b) Ẹ máa yàgò o, bọ̀lọ̀jọ̀ ń bọ̀ lọ́nà

A éè ó eee

Ẹ máa yàgò o.......

Lẹ́yin ìwọ̀n àkọ́kọ́ tí a yà sọ̀tọ̀ fún pipe ohùn àti yíyí àwo-orin èyí tí àwọn apohùn ti pè oríṣiríṣi ohùn sí fún ìdánílẹ̀kọ̀ọ́ àwọn tí a kó jọ. Àbájáde ìwádìí wa fi hàn pé yàrá-ìdánilẹ́kọ̀ọ́ (bí àṣà) ìdá ogún nínú ìda ọgọ́rùn-ún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yìí ló lè pohùn mẹ́rin: pe ẹ̀sà ní 1, sun ìjálá ní 2, sun ẹkún ìyàwó ní 3, ki ẹsẹ̀ ifá ní 4, ki oríkì ìlú (Ògbómọ̀ṣọ́, Ẹ̀gbá, àti Ìbàdàn) ní 5, pe ọfọ̀ ní 6, àti kọ orin (arùngbè àti bọ̀lọ̀jọ̀) ní 7 nínú ewì alohùn méjèèjè yìí bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ nígbà tí ìda ọgọ́rin tó kù kò le è pohùn àwọn ewì yìí bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. Akiyesi wa ni pe nípa ìṣàmúlò yàrá-ẹ̀kọ́-èdè, ìda ọgọ́rin àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí a kó jọ ni ó lè pohùn mẹ́rin nínú àwọn ewì alohùn méjèèjè náà bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. Bakan naa ni a sakíyèsi pé, yàtọ̀ sí pé ìlo yàrá-ẹ̀kọ́-èdè so jinwinjinwin èso nípa pé kò fi àkokò ṣòfò rárá àti rárá, bẹ́ẹ̀ náà ni kò lani lóògùn lọ titi bíi ti isamulo yàrá-ìdánilẹ́kọ̀ọ́ (bí àṣà) lásán.

## Àgbálọgbábọ̀

A ti ná Ìgbárá a sì ti á Ìgboro nipa ìṣàmúlò yàrá-ẹ̀kọ́-èdè fún kíkọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ède Yorùbá ní ewì alohùn. Ìwádìí tí a ṣe ti fì ìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé ohun-èlo amẹ́kọ̀ọ́yéni tí ó ṣe pàtàkì fún kíkọ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá ni yàrá-ẹ̀kọ́-èdè jẹ́ àti pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ilé-ẹ̀kọ́ gíga wa àti ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ ède Yorùbá ni kò ní yàrá-ẹ̀kọ́-èdè tí ó pegedé tí ó lè mú kí ó rọrùn fún àwọn olùkọ́ tí ó ń ṣàmúlò rẹ̀ àti kí akẹ́kọ̀ọ́ ṣe àṣeyọrí nínu ohùn pípè. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ní ìbẹ̀rẹ̀ bébà yìí pé àwọn tí wọ́n sọ ède Yorùbá di kíkọ sílẹ̀ kò lè lérò pé ède Yorùbá yóò di ohun tí à ń fi ẹ̀rọ ìgbàlódé kọ́ ní àkọ́yege, ó yẹ́ kí gbogbo àwọn olùkọ́ èdè tí wọn kò tí ì mọ bí a ṣe ń lo yàrá-àyẹ̀wò èdè pakiti mọ́lẹ̀ kí wọ́n lọ kọ́ bí a ṣe ń lò ó kí a lè bá ìgbà yí bí ó ti ń yí, èyí ni kò ní jẹ́ kí á wà lẹ́yìn.

Àwọn aláṣẹ ilé-ẹ̀kọ́ gíga wa gbogbo gbọ́dọ̀ ri dájú pé yàrá-ẹ̀kọ́-èdè tó gbámúṣẹ́ wà ní ilé-ẹ̀ko wọn, kí wọ́n sì ṣètò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó yanrannti fún àwọn olùkọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá tí yóò máa kọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wa. Níbi tí àwọn aláṣẹ kò bá ti ní owó fún ṣíṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn olùkọ́ èdè àti lítíréṣọ̀, kí wọ́n gbìyànjú láti máa gba àwọn apohùn lóòrè kóòré tí yóò máa wá fi oríṣi ohùn kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn nínu yàrá-àyẹ̀wò èdè. Èyí kò ní jẹ́ kí iná ewì alohùn jó àjórẹ̀yìn àti pé èyí yóò tún jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó bá dángájíá nínu ewì alohùn lè fi ṣe iṣẹ́ ṣe bíi ti àwọn Ajóbíewé lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ wọn.

Ní àkotán, ohun-èlò amẹ́kọ̀ọ́yéni tó dára jùlọ láti fi kọ́ ewì alohùn Yorùbá

ni yàrá-àyẹ̀wò èdè ń ṣe nítorí ìlo rẹ̀ bá àkokò rẹ̀, kìí lani lóòógùn rárá, ó sì tún mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ èso rere jade. Ìlo yàrá-àyẹ̀wò èdè lọjọ́-ọ̀la fún kíkọ́ èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá yóò jẹ́ kí èdè àti àṣa Yorùbá jẹ́ ọba nínú àwọn èdè àgbáyé tí ó ṣe pàtàkì jùlọ.

## REFERENCES


Adegbija, E. (2004). Language policy and planning 5(3). hhttps://www.bookpump.com.

Aziza, R. (2010). Nigerian languages, teaching and usage: Problems and prospects, Nigerian languages studies 2 (1). 21-31

Hayes, A. S (1968). Language Laboratories Facilities: Technical Guide for their Selection, Purchase, Use and Maintenance, Oxford University Press.

Perez-Paredes, P. (2002). From Rooms to Environments: Techno-Short-Sightedness and Language Laboratories, International Journal of English Studies (IJES), 2(1). 59-80

Tionio, N, (2001). Communicative Listening in the Language Laboratory, 2 (2). 73-82

Ugwu, A. I. (2008). The Relevance of Igbo Language in Colleges of Education, Journal of Languages and Literature (JOLL), 2(2). 76-86

Maheshwari, V. K (2016), Language Laboratory, The open Educational Resources (OER).